# ENMO! DOKITA GBA OWO LOWO OKU ORUN




SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.



ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



U. T. C.
SERVES
YOU
WELL


VOL. No. IX 522. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, JUNE 1, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

## Dokita gba owo lowo Oku Orun

Dokita kan ti orukọ rẹ njẹ Jọnu Adamu nilu kan ti a npe ni Eastbourn nilu Oyinbo ni a gbọ wipe awọn adajọ marun nṣe abẹwo ẹjọ rẹ. Ẹsun mẹdogun ni awọn ọtẹlẹmuyẹ fi siwaju awọn adajọ yi pe Dokita Adamu gba owo lọwọ oku ọrun, o si tun ṣe madaru ninu iwe isinku.

Laipẹ yi ni Dokita Adamu bọ okun lọrun nile ẹjọ nla ti a fi sun ẹsun wipe o lọwọ ninu iku alaisan iyafin, Alice Morrell, nitori ki o le ko ogun rẹ. Iyafin Alice yi, awọn ọlọpa ni o jọ ẹniti o ni owo pupọ, o si gba Adamu ni dokita pe ki o ma tọju on ki ẹmi on legun siwaju si. Dokita Adamu ni eleyi ko le ni owo ki iya-owo tun ma jẹ on. O wa ọgbọn ti o fi ba obinrin na sọ wipe ki o fi owo fun on ninu iwe ogun (Will) rẹ.

Agbalọ-agbabọ, awọn ọlọpa ni Dokita Adamu ba iyafin Alice wa egbogi fẹhinjan-omi lẹhingbati o ti ṣe iwe rẹ ni b'o ti fẹ ki o ṣe tan.

Ikan ninu awọn oṣiṣẹ. Nọsi Dokita Adamu jẹri wipe on wa nibikan nijọkan ti Dokita nbere lọwọ ikan ninu awọn alaisan rẹ ti orukọ rẹ njẹ James Downs wipe, ṣe ko ni fi owo fun on ninu ogun rẹ ki o to ku ni.

Bi a ti nkọwe yi, wọn ṣi wa ninu wọn nro ẹjọ Dokita Adamu lọwọ wipe o ko egbogi buruku pamọ ati Madaru ti o ṣe si iwe oku.







THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG


## Ife Fadaka



Ohun ti a nwo ninu aworan yi ni Ife Fadaka ti awon oyinbo fi ta Ile Nigeria lore fun aworan kan ti nwon ya ti o niyi, ti o si leye l'oju gbogbo awon to wo aworan na.

Awon to ya aworan to yege to si gba ebun yi je awon ayaworan Ile Ise alarina Ijoba ti a npe ni Federal Information Service l'Eko.

## Kilose Ti Won Fi Nsa Fun Sosi

Olotu,

E jowo e gba mi laye lati fi Simiyon Aralamo lohun fun ibere re ti o wipe kilose ti won fi nsa lati lo sile esin ti a npe ni Sosi.

Lojo tani o dahu enipe ife ti won pa ni ikoja o'in ko si ninu awon Onigbagbo mo. Bi o ba wipe ki o so otito inu re ni awujo ni Sosi won a ma fi ogun re welo kiri. Ijo ngba iyawo alufa, alufa papa nyan iyawo lo ni ale.

Nitori asa ati owo loku ti a nlo san ni Sosi. Bi o ko ba lowo ko ni moto ki o lo ma owo bi oloda ni ibi Ikore, alufa ko ni mo o.

 Irankowo ko tile si larin Onigbagbo si Onigbagbo mo. Eyi na lo nje ki a mo sa lati lo si Sosi.

Emi ni,
IWA LESIN.

O sirisi awon oriki lo wa ti ati gbo ti awon enia nje, awon ode awon jagun ja awon Onisegun awon Babalawo awon alagbara awon omiran ati awon enia bawonni. Die ninu awon Oriki na ni wonyi:—

Ogbajulogun omo ajo nikan ogberi odo ja bi oji ogbeni efon sa siladila Onamo ki iyi re tun na Adifa gba ore Okansoso alanoku ni Igbo kijikiji Ogberi olori kile ninu orun gangan Areki-jobi Ogelon re ibi ila Elepa Isana Arele igi jogun Abikute fun ogunja ati awon oriki bebe.

## Kilose Ti Won Fi Nsa Ni Sosi?

Olotu,

Ore po ninu ibere Arelamo ti o wipe kilose ti a fi nsa lati ma lo si Sosi. Emi ti o ba bere oro lo sfe idi re gbo. Onigbagbo ni emi. Egba si ni mi. Mo si ro wipe ti nwon ba nsoro nipa bi Igbagbo se de ilu Iwo-orun Afrika, awon Egba papa ko nse e iti a le fi owo ro si ehin.

Mo ro wipe owo igba alufa lo sle won sa ni Sosi ati pe nso orisirisi ti elomiran ko ni lati mu lo si ajo Sosi. Opolopo papa ni owo ijoko ti a npe ni piu (pew) nle sa. Awon obi elowo miran ti o ni owo lowo lati ra aso ati lati san owo apo alufa, idi yi ti ko je ki awon le wa. Afowofa wa ti po ninu aye.

"Ilowo—i a i y e—m o" Nitoto o dala enipe Igbagbo ti ekuro nile aiye. A ko sin Olorun mo owo lo ku ti a nsin. B'otito ti tan ninu aiye, bo ti gba loku to ni aiye.

Boya Arelamo ti o kowe ri pe awon enia ko npo pupo ni Sosi ilu Aganyin, ni Nigeria nlo sugbon okan wa ko ti ni Sos.

Emi ni
Kekere Igbagbo

## Awon oriki Nile Yoruba

Orisirisi awon oriki tabi awon alaje oruko ti a fi npe enia nile Yoruba po idi re ti a fi nje oriki yi ni wipe ki eniti a mba soro le tete mo eniti a nsoro re. Nitoripe bi a ba nsoro nipa Adamu iru awon enia ti a npe ni Adamu po jojo lorile aiye.

Oro Adamu Ilorin ni mo fe ba so sugbon nigbati mo daruko Adamu eniti oluwa re mo ti nwon pe ni oruko yi po. Nitorina ki oro yi ba le ye enia mo mba soro yi ni bere wipe Adamu wo niyen?". Ki o ba le ye eniti mo mba soro na ngo wipe Adamu Elempe alaiyi ti oro na yio fo wa ye eniti mo mba ro wipe Adamu Ilorin ni mo nwi.

## Nwon Se Ajodun Orunmila Nile Eko

Lojo Isegun ti o nse ojo 14th osu Ebibi (14th of May 1957) ni ojo aisun odun Woli, tabi oluse mimo ti a npe ni Orunmila. Pupo ninu awon Ile Ijoba Olodumare ti awon Ijo Olorunmila lo se isin aisun na, awon ijo miran se ariya nibi apejo won.

Nile Oloye Adesina Awolunde Ajanaku, Araba ilu Eko, aisun na bere lati agogo mesan ale (9 P.M.) titi di owuro ojo keji. Bi awon ti nse ariya yi ni Eko, be ni nwon nse ni agbegbe re.

Lojo 15th osu na lati owuro di asale ni awon apejo Ijo Olorunmila se iwasu ni igboro ilu Eko ni Ebu-Owa eniti o se iwasu lojo na ni Eni owo Oduseyi Solayo ti o nse oloye Aseda fun Ijo Adulawo. Lojo 19th osu na ni gbogbo omo egbe yi se isin idupe nile ijin won ni Idumagbo. Ogbeni O. Osira ti o nse oloye Akoda lo se wasu.

Nwon yo ayo lo sile oba o si ba won soro isiri pupo lehin ti oba pari oro re Ogbeni Ajanaku ti o nse Oloye Araba Eko dupe fun oba fun oro iyanu ti o ba won so nipa isese ile Yoruba. O gbadura fun oba ati Ijoye o si gba fun awon ogalu wa to lo sile Oyinbo fun eto ilu.

Die ninu awon ti o wa nibe ni, Asoju awon Babalawo, asoju awon Onisegun asoju awon Jagilegbo Ijo Adulawo, Ijo Olorunmila, Ijo ibile Enia dudu. Lehin ti nwon kuro nile oba nwon pada sile Ajanaku.

## Ise Simenti nfe bere nile Nigeria

LONDON

Awon iko ti o lo sile Oyibo fun idagbasoke ati ilosiwaju ni ile wa ti se adehun pelu awon olotu Oyinbo ti nse ise Simenti lati wa bere ise na ni agbegbe Iwo orun ile Nigeria nitori okuta re mbe niha ile Yoruba.

Lojo Jimo 17th osu May 1957 ni Ogbeni Rewane ti o nse adele Alaga igbimo W.R.P.D.B. towo bo iwe fun awon Oyinbo ti o mbo wa sise Simenti na.

Ko nse Simenti nikan ni awon ma se nwon o tun bere ise Roba pelu tabi awon ohun gbogbo ti a nfi roba se.



## S. L. Akintola

Eniti a nwo ninu Aworan yi ni Oloye S.L. Akintola ti o si je okan pataki ninu awon onimoran fun egbe Afenifere (Action Group) o wa ninu awon enia pataki ti awon omo Akekoranse pe lati wa si apejo nla kan ti nwon ti pese sile fun won. Nibi apejo na ni awon enia wonyi wa. Oloye Awolowo, S. L. Akintola Rosiji, Rotimi Williams, ati awon enia jankan-jankan bawonni.

# Ebun asiko ojo niyi

## Wa je 375,000/- ninu

Orire ti S. C. L.

Eniti o ba yege ninu orire na yio je 355,000/- eniti ila kini ati ekeji tire ba dogba po pelu tiwa yio je 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

șe eto awon nomba lati 15 si 30 sinu ojule kokan, tobe ti arope re lati oke si osi, lati oke sisale lati igun kini sisale igun keji je 90. A ko gbodo

jeki nomba kan po meji n'nu re. Ojo ti a ko ni gba iwe lodo eni kan mo je 24/6/57,
E fi gbogbo iwe nyin ran oko ofurufu, Esi re yio jade ni 30/6/57,

| Last Result Total 82 | | | |
|---|---|---|---|
| 26 | 18 | 15 | 23 |
| 27 | 19 | 22 | 14 |
| 16 | 24 | 17 | 25 |
| 13 | 21 | 28 | 20 |

Owo eyo kan 20/-. Fun merin 40/- Fun merin dilogun 80/- Fun merin lelogun 100/- Fun meji lelogbon 120/-
OPIN:- Eniti o ba fe se pupo, le se sinu iwe miran bi o ti fe. Postal Order tabi Money order ni a fe Nomba ti Owo ni a fe

eniti orire tire ba dogba po pelu tiwa ni ao gba pe o yege
Eniti o ba fe gbo esi ki o fi 1/- owo oko kun owo tire
Sugbon bi o nfe kiakia fi 2/- owo okò ofurufu kun owo tire
Ko si eje nibe, ayi ti a ba șe ni abe șe.
Fi owo ati orire ti re ranse si,

**S. C. L. CORPORATION**

MANIK CHOWK, P.O. 12, ALIGARH CITY (INDIA)


# O ni Koko Nilu Fanandopo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Farnandino ti o nșe egbon fun iyawo adajo Ogbeni Rhodes, o ni oko Koko nla ati oko Kofi, on ni eniti o gba Oloye S. L. Akintola lalejo nigbati o lo be ilu Fenandopo wo ati Rio Munis. Ni asiko ti nsoro re yi ni Oloye tiwa S. L. Akintola mbe lori oye Alakoso itoju awon osise (Minister of Labour).

# Irohin ipade nilu Oyinbo

LONDON. Ni owuro ojo 23rd osu May 1957 ni ipade bere nilu Oyinbo nipa bi ominira ile Nigeria yio tise rorun. Olukuluku awon to lo nitori apejo yi bere si de, eyi ti o woko (Train) eyiti o wo moto, eyiti o woko Trana Nigbati Sardauna de nșe ni așo re nfe lele.

Ninu ipade na, Macpherson ti o koko je oye Governor General nilu Eko dunwo nigbati o ko așo oye re wo. Lehin na ni Dokita Azikiwe de rinu așo ibora funfun, o bo sile ninu moto re. o si nfe wole lo ni oyinbo ti nwon fi șo oju ona ba taku wipe, a gbodo Dokita Azikiwe ko gbodo wole, ayafi bi o ba le fi iwe ti nwon fi pe han on.

Dokita Azikiwe bere si tu așo re, ko si ri iwe na, ni Oyinbo na ba da a duro wipe ko gbodo wole. Ara awon to wa nigbimo na lo yara tete so fun Oyinbo na wipe okan ninu awon ti Lennox Boyd fe ba soro nuni, lo ba jeki o wole.

Lehin ti gbogbo awon igbimo ti joko tan, nigbana ni Ogbeni Lennox Boyd dide duro, o si ki gbogbo won bayi wipe "Inu mi dun gidigidi, lati ki gbogbo enyin igbimo loruko Alaiyeluwa oba obinrin ilu Gesi wipe, e ki abo, șe alafia ni e de"?.

Eniti o tun soro ni Sarduna Sokoto, o soro ti o wa enia, Lehin na ni Oloye Awolowo soro bayi pe. "Fun opolopo awon ara ile Nigeria, ile koji ni ilu Gesi je fun won nitorina, wiwa ti a wa sihin ko nșe arin alejo ni a wa bi kose pe, a wa sile wa keji. Ati nigbati a ba di ominira tan, yio je ohun iwuri fun wa lati wa nirepo pelu Ijoba Gesi. Ohun pataki ti awon ba wa ni lati gba ominira fun Ijoba Iwo-orun, ati ominira fun apapo Ijoba ile Nigeria 1957, ati eto ti yio jeki ile Nigeria wa ni ominira titi aiyo, ki a si gbohun si ara wa lenu.

Eniti o tun soro ni Dokita Azikiwe o dahun wipe, larin odun merin ti a ti nșe Ijoba bowa, ni Gesi ati ile Nigeria di ore po tobe ti nwon fi ni lati sin wa de ebute ominira, o si daju wipe oro yi ni gbogbo awon te pejo sihin wa so. Gbogbo awon enia on to wa sihin, nitori ki oro na le je bi awon ti nfe ni nwon ti se wa.

Nihin ni oro yi kan Dokita E. M. L. Endeley O dahun pe ko nșe nitori ki nwon le ma șe akoso awon ni kanșoșo ni awon ti șe wa si ilu Gesi, șugbon nitori ki awon le ri opolopo owo lati fi tun ilu won șe ni. Nipaki ișokan ilewa ni a nfe.

Governer General Sir James Robertson ti o nșe Gomina agba nilu Eko so wipe, ișe ti ao șe loni lati șe ofin gegebi a ti fe ki ile Nigeria ri yio le die pataki ișe na yio wa lori awon onișe oba eniti o ti mose daradara lo le gbe ișe ominira duro.

Bayi nipade akoko pari ișe owuro awon o tun pada wa losan Lennox Boyd pașe be. Gbogbo awon igbimo na tuka kakiri agbegbe ile igbimo na a ko șaiși ari awon igbimo bi meji tabi meta ti nwon mba ara won soro nipa ohun ti awon o muse ni osan.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

**E L E T I Q F E**

A-NIJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

18, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"

P.O. Box 467 Phone 23370

VOL IX. NO. 522. LAGOS, SATURDAY JUNE 1, 1957

# Ipade Bere Nilu Oyinbo

Gegebi irohin ti a ri gbo lati owo Alakeso ise Iwe irohin wa, inu wa dun lejo lati gbo wipe awon Olotu wa bere ipade won pelu gbefe ati inudidun pelu ife to yekoro si arawon.

Kosi ohun kan ti o le dun mo gbogbo wa ju eyi lo, paapa bi a ba ri ti owo girimoyan ti a fi ran awon Olotu wa na lo lati jiroro po pelu arawon lori ilosiwaju ile wa Nigeria.

Gegebi a ti so wipe bi a ba ro ti owo girimoyan ti a fi ran awon Olotu wa wonyi lo, o nilati je ohun idunnu fun wa nigbati a ba nri ti owo wa na nilu na, iyen ni wipe, nwon ko lo pa owo loku lohun ise ti nwon ba lo tara ni nwon nfi gbogbo ara se fun idagbasoke ilu wa.

Ni pataki, oro Oloye wa Olola Obafemi Awolowo ti o nba awon enia so nilu Oyinbo lohun fihan wa wipe irepo ati ifohunsokan mbe lati fi se eto ilu wa ti yio yo'ri si rere.

Afi wosika wa yi da muso fun awon Olotu wa mitetu fun irohin ti a gbo yi, asi ni ero wipe bi won ti bere daradara yi, nwon yio pari re si daradara.

Ki Oba Oluwa rere fan won lowo

---

**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT :

**Okunowo Brothers**

63 Massey Street, (Paji Market)

LAOOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

# Gomina agba fun ile Wesingisi



Ogbeni Lennox Boyd ti o nse Sekiteri agba ti ilu Oyinbo fi ye wa wipe Ogbeni Lord Hailes ni Oba obinrin yan lati je oye Gomina agba fun ile Wesingisi (West Indies). Iwonyi ni awon ilu ti yio wa labe ase Gomina na, Antigua, Barbados Dominika, Grenada, Jamaika, Montserrat, St. Kristopher Nevis Anguilla, St. Lucia, St. Vincent, Trinidad ati Tobago.

---

IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nbe omode ja ni asiko ebin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

---

Polowo oja re sinu iwe Irohin Eleti - Ofe

# Awon Kiriyo Tun De o!

OLOTU. Gba mi laye ninu iwe irohin re oloyin momo lati tun kede si eti gbo enyin Musulumi wipe awon elesin Kiriyo tun de o.

Ninu ipade igbimo ti awon alufa Kiriyo se laipe yi. A gbo wipe, odidi alufa kan lo damoran wipe, ki awon omo kiriyo mase gba ohun kan lowo awon Musulumi lasiko ti nwon nse odun won beni ki awon mase fun won ni ebun. Ati ni akoko odun Kiriyo ki awon mage fun Musulumi ni ebun ohun kan, beni ki nwon mase gba lowo won mo.

Ko nse oni gi awon Kiriyo ti ndite bayi, lasiko kan ni awon se igbimo, ti nwon so pe ko to ki omo kiriyo ma ra eran je ni oja nitoripe nwon nkewu si ki nwon to pa a. Asiko na ni nwon nko orin yi, "Ab'egungun m'u ti, a borisa jebi, esel melemo, kiriyo nj'eran imale.

Katile so ni ti gasikia, Musulumi po ju awon Kiriyo lo lona kona eru ko ba ejo, eniti o ba te ejo mole oluwa re ni ebo mbo.

Emi ni.
Alufa Epe

leti nipa igbimo kan ti awon alufa ijo Kiriyo lo] se laipe yi, ninu eyi ti nwon fi ohun sokan wipe:-

Nigbati awon ijo Kiriyo ba nse odun won ki nwon mase pe awon omo Imale sibe, ki awon ma si se fun won ni ebun. Ati nigbati ijo Imale ba nse odun, omo Kiriyo kan ko gbodo lde ibe, bi nwon ba si fun won ni ebun ki nwon ma se gba.

Enyin omo Imale, ewo ni eri so sinu oro yi o?

Emi ni.
Alufa Ojiko.

# Asoju Wa Pataki



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Alimi Adegbemi Bisiku, eniti o ti le se owo si Oke-okun, nile Aganyin, o wa bę ile ise Eleti-Ofę wo.

Ohun pataki ti o mba lo si Ede ilu re ni wipe, Joseph Adeniran ti o nse baba kekere fun alejo wa yi ni awon fe fi joye Balogun ilu Ede.

Lehinti awon ba pari ti oye jije tan, alejo wa yi pelu Disu Amonbi ti o nse omo re, yio ba oko ofurufu lo sile Ghana.

Alejo wa yi lo yombo iwe irohin wa pe, Eleti-Ofę kun fun Ogbon ati oro amoye si po ninu re. Niterina on gba gbogbo awon Yoruba ti o mbę ni ilu Kadjebi ati Okeokun ni imoran lati ma ka iwe irohin na. Eniti o ba si fe ra iwe Irohin Eleti-Ofe na, yio rira lodo:-

A Adegbemi
O. K. Store
Box 16 Kadjebi Ghana

**E Ma Ka Iwe Irohin**
**Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun**
**Ki E Si Ma Polowo Oja**
**Yin Sinu Re**




Have a
Capstan

*they're blended better*

# Kini Awon Kiriyo Fe Dauwo Yi?

OLOTU. Gba mi laye lati si awon Imale

## Ilu Ibadan Fe Gba Awon Alejo

IBADAN, A gbo wipe awon enia mejidiladota ninu awon omo akoko ti o mbe kakiri University agbaiye, yio wa si ile Nigeria, lati se ibewo sipa Ibadan University College. Nigbati awon ba si de, ninu ile University ti Ibadan ni awon o de si ni apa ona Eleyele.

Ninu awon omo akoko ti o mbo ye marundiladota ninu won je omo ilu Kanada, awon meje ti o ku je omo ilu Amerika.

Awon osise British Council yio lo si ibuso won lati ri awo'an bas won nipa apejuwe ile Nigbati (Geography) Lehin eyi ni awon oniwe irohin yio lo ba won soro nibiti awon de si, awon o si fi oro we oro fun ara won.

Lehin na awon o pin ara won si ona meta, apa kini, yio lo sile Ibadi, apa keji yio lo sile Ife. Sugbon awon apa keji yio pin si ona meji, ona kini yio lo si Akure, Idanre, Ondo, Ado Ekiti, ati Ilesha, awon o lo pade awon ona keji ni ilu Akure awon ona keji yio se ibewo ilu Oshogbo, Ilorin Jebba, awon apa Keta yio duro ni Ibadan ni Ibadan, awon o lo se ibewo ilu Abeokuta, Ijebu-Ode, Ife, ati Iseyin.

Nigbati o ba di ojo ketala osu June 1957, awon o pada sile won. Nipe bayi, gbogbo ire ti awon ri ngbo nipa ile Nigeria, y'o se kadara loju won.

## Isifa Sosi Kan Soro omoluwabi

KADUNA Lehin ti awon pari ipade Sinodu kan ni apa Isale Odo Oya, ni awon tun bere ti Oke Oya nilu Kaduna.

Oruko ti awon alufa ti o mbe nibi ipade na so bayi, wipe, ori egbebi alufa ojise Olorun, ni kesi gbogbo awon omo Kiriyo jake-jado ile Nigeria wipe, ire ati ilosiwaju ile Nigeria, ni ki awon ma lepa.

Alufu na tun se alaye wipe, ohun ti a fi mo Onigbagbo tooto ni wipe, oi wa re yio je oledo, yio ni ife si gbogbo enia, yio si je omoluwabi, ibiti awon ngbesawo ni yio ma wa, ko ni si nibiti awon ati yigi.

E je'ki a parapo, ki a fi ara wa sokan gegebi a ti npe lati ehin wa, ko mase si okan ni ti Paul, okan ni ti Appollo. Ni sise bayi, alejo ko ni ridi wa, enia wa ko si ni han sode.

## Ijagboro Be Sile Nilu Orlando

A gbo irohin wipe ijagboro be sile nilu kan ti a npe ni Orlando ni iha Gusu ile Afrika. Bi oro na ti lo niyi :-

Awon enia bi ogun ni awon olopa ranu fun origirisi ese, nigbati awon olopa si nko won lo si sobu olopa, nse ni awon egbe won ya de, awon lu awon olopa na ni alubole, awon ti awon mu si tuka.

Nigbati ose ni ogun awon olopa de pelu ibon ogun si bere lasin awon olopa ati awon ara ilu na. Ogun na pa enia dudu meji, merinla fi ara gb'ogbe. Oyinbo wa ninu won.

Ibon Sten gun ni awon olopa lo lojo na ija na po gidigidi, olomo ko mo omo re mo. Awon olopa si nwa awon ti o se ti awon mu ki ijagboro ni to sele lori won.

## Eniti Ko Peni Wa Jeun Nse Ara Re

Onje ti enia eje lo nfun enia l'okun ati agbara, bi enia ba si ti fi onje die sinu, bi oka, fufu, amala tabi iyan, eyini le gbe oluwa re di nsale bi eni na ko ba ri onje miran je.

Eniti o ba ri onje ti o ajeun ti ko si pe enia wa je, ara re lo ndi eru ru, nitori bi o ba fe, o le je gbogbo onje na tan, on nikan ni yio ma ru eru re kiri o di'iju pe, yio tewon je eniti ko ri je lo, sugbon ki o ma toju agbo jedi-jedi.

Eniti o nfe jeun ti o si penia wa je oluwa re nfe alafia fun ara re nitoripe eru ti on nikan iba di si agbedu re, awon elomiran yio gbe eru na si agbedu tiwon, awon yio ran lowo eru tire si fuye.

Owe Yoruba kan so bayi pe, didun li odun ti a fi mba ore jeko, tile ege to oga je.


### Kere o!

A ti ni origirisi ogun German to sese de, fun onigiru aisan tokuurin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.



## CARSON PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28 BALOGUN STREET LAGOS

## Omo egbe Afenifere lo pade awon iko lokun

SEKONDI Awon omo egbe Afenifere ti o mbe ni Oke-Okun yan awon enia pataki larin ara won ti awon lo pade awon iko ti o lo si ilu Oyinbo fun eto ile Nigeria ni agbami okun.

Nwon yan enia lati ilu Accra, Cape Coast, Nsawam Kumasi, Abuso, ati opo ilu miran lati lo pade won ni Takoradi.

Oloye Akintola ba awon egbe Afenifere soro lesiri lehin na, nwon bo sile nwon si ria ebute Takoradi wo, nwon si ba awon Oniwe irohin soro die. Lehin eyi, ni won lo si Sekondi nibiti a gbe ti pese ile arewa nla kan die fun adiye ojo na.

Ki awon to dele ile yi ogunlogo awon Yoruba ati Aganyin lo ti jo joko de awon alejo wa ni ibe. Ogbeni Ayo Rosiji lo si toka awon omo egbe ti so wa sibe. O fi oba Ado Ekiti han, Eyini igba akoko ti awon Aganyin foju kan oba ile Yoruba.

Awon to soro ni Oloye Akintola, oba Ekiti, Alhadji Maito, Olawoyin, Aminu Kano, ipade na dun bi eyin awon si mba tiin ajo won lo.

---

### IGBIMO AJO BABALAWO

OLOTU Eyiyi ni leti fi so fun gbogbo awon Babalawo ti o mbe nile Ki-aro, o jire, loke Oya ati loke Okun wipe, Igbimo ajo Babalawo yio wa ni 8th ogu Okudu (June 1957) Nile Igara lupa agbegbe Ijebu Remo ni a o ti se.

Ipade alapero ni a o se ni agogo mefa irole ojo eti ojo keje ogu Okudu.

Ipade wa bi oyin. Aso

G. A. Dosunmu

Akede gbogbo-gbo

Ijo Babalawo Nigeria.

AKIYESI

A afe awan asoju kakiri ile Yoruba, ni Oke Oya ati ni apa ona Oke Okun ni ilu Oyinbo.



# Ade'le Ba're o.



Nigbati ailera de si alagba Sir Anthony Eden ti o fi ohun ti ko le se ise ijoba mo, nwon gbe lo sile iwosan kan nile Kanada o si wa lori ibusun aisan fun iwon ose mefa.

Nisisiyi, ara re le die, o mba oko oju omi kan ti nmo npe ni Empress of Britain bo wa sile.

Oba obirin Gesi ti gbo wipe, okunrin alagba na mbo wa sile, nitori eleyi, oba na pase wipe, ki oko ofurufu ti oba nlo ti npe ni Viking lo duro de Ogbeni na nitori ibiti oko oyinbo na yio gunle si, ki o si gbe lo pelu iyawo re lo si ibuso oko ofurufu to sunmo ile ilu re ni Wiltshire Country.

# Oyinbo ile Hausa kan lo soro yi

LONDON. Oyinbo kan nile Hausa, ti o nse Baba egbe fun igbimo Assembly le ... yi nilu Oyinbo wi ... ti a ti se npin owo ododun larin awon ijoba yio je okan ninu ohun ti oro re ko ni se yanju, nigbati ominira ba de sile Nigeria.

Sugbonpe awon die nino awon enia gbogbo wipe, agbegbe won ko nri owo ododun ... gegbi o ti to eyi ni je okan ninu awon ohun ti on sakiyesi pe yio ma da ijagbon sii edekoyede sile nigba gbogbo

O to, a si ye ki a ranti lati se eto nipa gegebi ao ti se ma pin owo ododun ti ko fi ni poju si apakan.

# Edekoyede fe wo igbimo Ilorin

ILORIN. Tele-tele ninu igbimo ilu Ilorin awon oloye ibile ti o wa nibe po die sugbon ni lolo yi eni kan damoran wipe o ye ki igbimo din awon ijoye na ku, nitori pe nwon poju.

Kini awon ijoye na gbo bayi si, ese ni nwon tito soke, ti

nwon si fi oju gba a die loku, oro na iba bi ige-bi-Adubi.

A gbo wipe meji ni awon ijoye na awon marun ni nwon yo kuro, o wa ku Balogun Gambari, ati Mogaji Bi oro na ba si ti tun nlo si ao ma gbo.

# Ajodun Awon Odomode Ilu Eko

EKO. Nigbati o ba di ojo Sunday 2nd osu June 1957, gbogbo awon odomode kakiri ilu Eko yio se ajodun omode ti awon nse lododun kakiri gbogbo ilu nibiti nwon gbe nso ede Gesi. Awon Kiriyo yio se ajodun ti won ninu ile isin ni agogo mesan owuro, awon omo Imale yio se adura ti won lojo Friday ninu Mosalasi Jimo Eko, nwon o si se itumo oro ti Oba Obirin fi ranse ni ede Yoruba.

Ajodun kini here lojo ti oba Joji (King George VI) Kefa nfe wuye, ese gbogbo awon odomode lo pe si West Minster lodun 1937. Lati ojo na ni awon ti ro si eto wipe beni o dara ki gbogbo awon odomode lokunrin ati lobinrin ma se ajodun yi lododun. Odun yi ni yio je akoko ti awon omo ilu Eko yi ba won lowo sinu iru ajodun be.

# Owe

A ko nse ere okiti loju obo, obo ni, ha, ise kini a se fi bi Baba on, oje, obo takiti ni gboro niso, gboro ye ye, gboro ye ye.









Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23370